# ALAFIN TUNTUN YIO JE NILU OYO



*AWOGBA Omode fun Girl, Ẹ̀yi, Hiku-chin, Orere.*
*Ra Tir Ni Ile Egbogi*
*— ISE —*
*Olodumare Okebolu, Ibadan.*
*116, Great Bridge St., LAGOS*

ELETI OFẸ
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

*TO CLEAR*
*Gents Suede Court Shoe Brown, Black & Grey Before 50/- Now 42/6*
Obtainable at :-
A. B. AKINYẸMI
*10A Moloney Bridge*
LAGOS

VOL. No. VIII 476. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, JULY 14, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)



T. O. S. Benson

Aworan yi niti Ọgbẹni T.O.S. Benson, Alaga Igbimọ ẹgbẹ Alakukọ Iwọ-orun, on l'o nso wipe, pẹpẹsẹ ki Ijọba Alapapọ (Federal Government) da si ọrọ Alafin ti Ijọba Iwo-orun yọ, ki nwọn o le da pada s'ori oye ọba nilu Ọyọ.

## ỌJỌ IDIBO DI ỌJỌ ISIMI NILU AGANYIN

Ọjọ Atalata, 17th oṣu July yio jẹ ọjọ isimi kakiri ni gbogbo ilẹ Aganyin, ni Aṣanti ati ni Togoland nitori ki gbogbo enia le ri aye lọ dibo.

Ṣugbọn ọjọ 13th oṣu July ni ọjọ isimi nilu Accra. Eyi ni akọkọ ti a gb'aye isimi fun ọjọ idibo nilẹ Aganyin.

## Nwon Yan Oba Titun L'Oyo

A gbọ irohin wipe lẹhin ti ijọba ti yọ Alafin Alhadji Adeyẹmi keji kuro lori oye Ọba Ọyọ nitori oriṣikun ... rẹ, awọn Afọbajẹ ilu Ọyọ tabi awọn Ọyọmisi wariko ... ẹniti oye ọba na ba tọ si.

A si tun gbọ wipe awọn ẹgbẹ N.C.N.C. ko awọn ẹgbẹ Ọyọ Parapọ s'odi lati ṣe atako si obun ti Ijọba Iwọ-orun ti ṣe.

Nwọn kọwe si Gomina Eko wipe ki o pa aṣẹ ti Ijọba Iwọ Orun ṣe rẹ. Ṣugbọn Ijọba na nṣe iṣẹ rẹ lafi ọta pe.

Awọn Ọyọmisi ti ṣe igbimọ nwọn si ti yan Ọgbẹni Bello Gbadegẹṣin ti o nṣe Arẹmọ fun Baba-Lafin ana, Ladigbolu.

A si tun gbọ wipe pupọ ninu awọn enia ti o ti faramọ awọn Ọyọ-Parapọ ri ti yi pada, nwọn si faramọ ẹgbẹ Afẹnifẹre Orukọ awọn Ọyọmisi ti o ṣe igbimọ yan Alafin titun na ni Baṣorun, Aṣipa, Jagun, Baba-yaji, Ọnaṣokun, ati Agunpopo.

Iṣẹ iṣowo ni Bello Gbadegẹṣin yi nṣe ki nwọn to wa yan ṣe Arẹmọ fun Baba Lafin ana Siyanbọla Ladigbolu. Nigbati baba rẹ si w'aja, o di ọkan ninu awọn Igbimọ alaṣẹ ibile Ọyọ.

A gbọ pe owọ ti mu orukọ rẹ lọ han awọn Ijọba Iwọ Orun nilu Ibadan.



Aworan ti ẹ nwo yi, niti ẹja Panla ti nwọn ṣeṣe nṣe iṣẹ rẹ lọwọ, nigbati nwọn ba ge ori awọn ẹja na tan, nwọn yio wa ti awọn ẹja na kọ gẹgẹbi awọn Imale ti ma nṣe so ẹran Ileya kọ nilẹ wa nihin, lẹhinti awọn ba ti ko gbogbo ifun inu awọn ẹja na kuro. Ni ẹ ni wọn yio ti gbẹ daradara ki o to wa di tita.

## THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited.

Ile ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ onişowo pataki ao ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun gbogbo ọja ilẹ wa ti nta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

# LAGOS RACE CLUB
# AUGUST MEETING
## Saturdays 21st & 28th July, Saturday 4th and Monday 6th August, 1956.

### FIRST DAY

| | | START |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Ten Furlongs Handicap Bottom Division | 3.00 p.m. |
| RACE No. 2 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 3.35 p.m. |
| RACE No. 3 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.10 p.m. |
| RACE No. 4 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 5 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5.20 p.m. |
| RACE No. 6 | Polo Scurry | 5.55 p.m. |
| RACE No. 7 | Eight Furlongs Handicap Top Division | 6.30 p.m. |

### SECOND DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 8 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 9 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 10 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 11 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 12 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 13 | Polo Scurry | 5. 55 p.m. |
| RACE No. 14 | Ten Furlongs Handicap Top Division | 6. 30 p.m. |

### THIRD DAY

| | | START |
|---|---|---|
| RACE No. 15 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 16 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 17 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 18 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 19 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 20 | Five Furlongs Handicap Top Division | 5. 55 p.m. |
| RACE No. 21 | Five Furlongs Handicap Top Division | 6. 30 p.m. |

### FOURTH DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 22 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 23 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 24 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 25 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 26 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 27 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5. 55 p.m. |
| RACE No. 28 | THE COMMONWEALTH STAKES 12 Furlongs - Top Division | 6. 30 p.m. |

# Ijoba Yo Alafin Kuro Lori Oye Oba



ALAFIN OYO

IBADAN Ijoba Iwọ Orun, ile Nigeria ti ro si etọ lati gba ade kuro lori Alhadji Adeyẹmi keji Alafin Ọyọ, enitì nwọn ti le sẹhin odi lati esi wa lasiko rogbodiyan ija igboro fi ṣelẹ ni Ọyọ lasiko ijọba re, ti ẹmi ọpọ enia fi rasu.

Ejọ ti ijọba ro ni wipe, nigbogbo asiko ti o fi mbẹ lẹhin odi ni Ilesha, ero ijọba ni wipe boya, yio wa ọna ti on yio fi mu ki ede koyede ti o mbẹ larin rẹ ati awọn ara ilu rẹ rọlẹ ki o ba le pada s'ori oye rẹ, sugbọn ọba yi ko se be.

Ọpọlọpọ ninu awọn enia to nifẹ si ọrọ Alafin yi, ngba ni imọran wipe ki o maṣe tẹle imọran eke ti awọn apakan oṣelu nṣọ fun, ati wipe ki o ma ṣe tapa si ijọba, ati wipe awọn Oṣelu burukụ ti o ba a damọran lati maṣe onikiXun ati lati ma tapa si ijọba ni ko jẹki ọran rẹ ti yanju kedere.

Gbogbo imọran rere awọn ti ni Alafin ko silẹ pasapata eyi ni ohun ti o mu ijọba Iwọ Orun lati kuku jade ot:tọ si oba na. A ko gbọdọ jẹ ki ilu kan wa laini Olori, ki o ma ba si idarudapọ. Nigbati awọn olufẹ ati ọrẹ Alafin ti fun ni imọran rere, ti o si kọ lati gba a, ijọba ro si etọ lati kuku gba ade kuro lori rẹ, nitori ko fẹ lati feti si oro ijọba rara.

Nitorina, Ijọba Iwọ Orun se ofin yi wipe, ati yọ Alhaji Adeyẹmi keji, Alafin Ọyọ, kuro lori oye ọba Ọyọ, ko gbọdọ de agbegbe Ọyọ ati Ibadan, Ijọba Iwọ-Orun yio si ma fun Alhaji Adeyẹmi ni Ọgọfa Poun (£120) losọsu, bi o ba ti tẹle aṣẹ ijọba ti ko si fa ijọgbọn nibiti o gbe wa.

Ijọba na yio fun ni ile to dara ti yio ma gbe l'ọfẹ.

ALAFIN TITUN

Nigbẹrẹ ti nwọn yọ Alhadji Adeyẹmi Keji kuro lori oye ọba tan, ni awọn enia merin, ninu awọn idile ọba ti njijadu lati j'oye Alafin titun, awọn Afọbajẹ Ọyọ ti bẹrẹ iṣẹ wọn lati mọ tani oye na to si, a si gbọ wipe idile Alafin ana (Ladigbolu) ni awọn Af'obajẹ yan.

A gbọ wipe awọn Ọyọmisi ti pe ipade kan ninu eyiti nwọn o se asaro, lori ẹniti nwọn fẹ yan na ki nwọn to gbe orukọ rẹ yọ'ju si ijọba Iwọ-Orun.

Irohin kan wa wipe Oloye Agbakin ati Oloye Alapinni ti awọn mejeji jẹ ọmọ ẹgbẹ Ọyẹ parapọ lọ sile Basọrun lọ ki i ati wipe nwọn se tan lati ran a lọwọ. Basọrun si ṣelere lati gba wọn pada sinu igbimọ Ọyọmisi. O sọ wipe ẹnikẹni ti o ba da ẹbi fun Ijọba Iwọ-Orun nipa ohun ti o de si Alafin Adeyẹmi ika ni oluwa rẹ fi se, nitoripe Alafin funra rẹ lo fa a.

## Eleti-Ofe Gba Alejo

Ko si bo ti ri ni ayọ ipade Eleti Ọfẹ pẹlu awọn alejo ti o nse Aṣoju ati ọkawe wa, nigbati nwọn de lati ilu Abidjan l'ọna Oke-okun ti nwọn nkọja lọ silu wọn lati lọ ṣe abẹwọ ile. Ọkọ ofurufu lo gbe wọn gunlẹ si Ikẹja, mọto onifaji ni nwọn si wọ de ile iṣẹ Eleti - Ọfẹ ni Alakoro.

Awọn alejo merin na jẹ enia pataki, gbajumọ ni nwọn si jẹ ninu awọn Onisowo, irisi oju wọn rẹwa, o si ndan. Orukọ wọn ni, Ọgbẹni B. Y. Karimu ọkan pataki lo jẹ ninu awọn ọmọba ilu Ejigbo. Ẹnikeji ni Ọgbẹni Jemes Babatunde, ọmọba Ilu Ejigbo ni on na nse. Ẹnikẹta ni Ọgbẹni Abudu Rahimi, Alabi ọmọ oloye Ọsọlọ Ejigbo ni on nse. Abu Bakare Bello ti o jẹ ẹnikẹrin wọn, on na papaa jẹ ọmọba.

Ki nwọn to lọ, nwọn ri Lemọmu Ajakuta, Ẹsọ Ikoyi ko si nile, awọn ri Olotu (Editor) pẹlu. Nisisiyi, nwọn ti ba ọkọ Reluwe lọ silu wọn, o di abọ ọkọ a re fo o.

# Western Region Production Development Board

## ACCOUNTANTS.

The Western Region Production Development Board has a vacancy in its accounting organisation for an Accountant. Candidates should possess a recognised accountancy qualification and should have had several years experience since qualifying including work on re-organisation, introduction of new accounting systems and budgetary control and most essentially some knowledge of costing and cost system with the ability to design cost systems. Commencing salary excluding inducement allowance will be in the range £1,100 - £1, 590. The point of entry will depend on experience and qualification.

2. Inducement allowance is £270 - £300 depending upon the point of entry.

3. The terms of service include partly furnished accommodation at 8 1/3o/o of the basic salary (excluding inducement allowance). free medical sevice, outfit allowance of £60, free first-class passage for wife and also free first-class passages once each way per tour for children up to three in number not over the age of thirteen. Employees are required to contribute up to 10o/o of the salary to a Provident Fund which is matched by equal contribution by the Board and which carried interest at 2 1/2o/o. Normal length of tour 18-24 months followed by home leave at full pay at the rate of 5 days per month of overseas service.

4. Applications in duplicate together with details of age, experience and qualifications and the names of three personal referees should be sent to:

The Personnel Secretary,
W. R. P. D. Board,
Secretariat,
Ibadan.

Closing date July 21st, 1956.

5. Only applications of those selected for interview will be acknowledged.


## IJAGBORO BE SILE NI-ILU POLAN

POSUNAN. Irohin ko to afojuba ni ijagboro to bẹ silẹ nilu Warsaw, iru eyiti a ngbadura ki Olọrun maṣe jẹki a ri iru rẹ nilẹ wa nihin awọn ọdunrun enia ni wọn pa danu ẹmi wọn.

Ohun to fa idi ija na ni wipe, awọn Oṣiṣẹ sọ fun Ọga wọn wipe, owo iṣẹ wọn kere, nipa bayi nwọn ran awọn enia mẹsan gẹgẹbi Ikọ lọ silu Rọṣia wipe ki nwọn ba awọn ṣe e, ki owo oṣu ga s'oke, ki owo onjẹ lọ silẹ.

Eyi ni awọn ọmọ Akẹkọ ti University gbọ nigbogbo wọn binu da iṣẹ silẹ. nwọn si tilẹkun ile ẹkọ wọn awọn ọlọpa inu de ibẹ, nwọn ko ṣilẹkun fun wọn, nwọn ko itọn ati ẹtu, nwọn rda'na si awọn ọlọpa inu, awọn na si nyin'ọn pada si wọ.

Awọn Ikọ ti awọn oṣiṣẹ ran lọ si Rọṣia, ko pada de mọ, eyi fa ibinu fun awọn oṣiṣẹ, gbogbo wọn da iṣẹ silẹ. nwọn ko ibọn ati ada, o di ọgba ẹwọn, nwọn fọ ilẹkun, nwọn ba nkan pupọ jẹ, nwọn si ko awọn Ikọ wọn jade. Lasiko na ni wọn yinbọn pa obinrin kan ati ọmọ rẹ, nigbana ni ori awọn ọlọpa wa gbona.

Nwọn yinbọn lu awọn Ọlọpa, beni Ọlọpa yin ibọn si wọn pada, nigbati ọwọ Ọlọpa ko ka mọ, nwọn ranṣẹ pe Ṣọja, ọrọ na wa kuro nijagboro, o di ogun ni paraku, ẹnikan ko le sọ bawo ni ja na yio tiri, bi a ba ti tun gbọ si, ẹ o ma gbọ.

## OJO ATI AGEGE DOGBA-DOGBA

(o bẹrẹ l'oju ewe kẹta

Awọn enia ti o si ti nja ijakadi nipa oju ọna yi ni awọn ẹnibi Lawani Ẹmiabata S. A. Abudu Mohamadu Disu ati Ologbe S lami. Ọgbẹni Lawani Ẹmiabata damọran fun awọn igbimọ wipe, bi o ba jẹ wipe ọrọ ovo lo ṣe idiwọ ti ko ni jẹki awọn nwọn tete ṣe oju ọna Moto na daradara ki igbimọ kesi on. Gbegbo igbimọ si ho ee-e-e nwọn si gbadun ọrọ rẹ.


### IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE
*(SILE MEJI ABO 2½d. FUN IGO KAN)*
O wa lọdọ :—
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS



E ma ka Iwe Irohin Eleti-Ofe L'osose, o kun fun Ogbon ati Irohin Aladun






**Awon ti e nsoro ninu ipade tabi igbimo feran siga Capstan Siga to dara ni**

# Irin Ajo lo silu Norway

## Lati owo TAJU THOMPSON

Iriri aiye ni a le pe irin ajo mi lọ silu Norway (Ilu Onipanla) laipẹ yi. Irin ajo na fẹrẹ gbe enia de opin [aiye l'ọna Ariwa l'ọhun. Alejo tio ba lọ lati ilẹ wa Nigeria nihin, ilẹ ti o ru nmu, si ilẹ otutu gidi ti a npe ni VARDO nibiti o jẹ wipe afẹfẹ ibẹ ati otutu ko mọ niwọn, yio ri wipe otitọ ni ọrọ owe ti o wipe "Experience is the best teacher" ni ede Oyinbo, ti a le tumọ si Yoruba bayi "Iriri ni ikọ enia l'ọgbọn".

Nitotọ, awa enia dudu, papa awa Yoruba fẹran alejo pupọ, ṣugbọn ilu miran tun mbẹ ti o ni ifẹ alejo gẹgẹbi ti wa. Bi a ba nwa enia ti o ni iwa rere, ti o si fẹran alejo, awọn ara ilẹ Norway ko idakan.

Irin ajo wa lati Eko silu nla London dara jọjọ ṣugbọn ọkọ ofurufu ti a wọ ṣe iyọnu fun wakati marun l'oju ọna, eyi lo mu wa duro ni ilu Tripoli tobẹ ti nwọn fi ṣe atunṣe rẹ, ṣugbọn irin ajo wa lati London si ilu Oslo, faaji ni.

AWỌN ENIA ILU NA

Awọn enia ti o mbẹ nilu Norway le diẹ ni adọjọ-Ọkẹ (£3,000,000) gbogbo titobi ilẹ wọn to 322,600 S.A.K. iye enia ti o ngbe ilu Oslo to ogun-ọkẹ enia (400,000) awọn ara ilu yi ni o wa ni ipo kẹta ninu awọn oyinbo ti o ni ọkọ ogun ti oju omi pupọ. O si di adọta ọdun nisisiyi ti nwọn ti gba ominira ara wọn. Ẹja pipa ni iṣẹ wọn pataki, ki iṣe ẹja Panla nikan (Abọmalọ) ni nwọn npa, nwọn npa ẹja Salumọnu, Herisi ati ti Sadini lọpọlọpọ. Nwọn nṣe takada, nwọn si nṣe ọti Bia, nwọn si mọ iṣẹ ọkọ ni kikan daradara.

IṢẸ IṢẸLU

Gẹgẹbi awọn ilu miran ni agbaiye, bẹni awọn ilu Norway nṣe iṣẹ iṣẹlu ti wọn, ṣugbọn wọn ko fẹran iṣẹ iṣẹlu tobẹ, iṣẹ nwọn ni nwọn nk'aramọju. Ẹgbẹ meji pataki ni ẹgbẹ Oṣe'lu to wa ni ilu Norway, awọn ẹgbẹ Labour ati ẹgbẹ Conservative. Awọn ẹgbẹ (Labour) ni o pọju.

Adọjọ ni iye ijoko igbimọ to wa nibẹ awọn ẹgbẹ (Labour) gba mẹtandinlọgọrin. Awọn si ni nwọn di opo ijọba mu, awọn ẹgbẹ keji Conservative gba marundinlọgọta, awọn ni nbojuto igbimọ kekere. Eto iṣẹ iṣ'elu wọn ba tiwa dọgba pupọ ni Nigeria nihin, ayafi ti Balẹ ilu (Mayor) ti awọn ma nyan ninu igbimọ awọn ilu pataki-pataki. Ninu Igbimọ Aṣofin ati igbimọ ibilẹ, ọdun marun kanna ni asiko ti nwọn nlo. Niba ṣoki bi iṣẹ ṣiṣe ati iṣ'elu wọn tiri niyẹn.

Emi yio m'ẹnu ba ilosi igbadun ti o mbẹ nilu Norway, eyi kun fun igbadun ti o jọ'ni l'oju ti o si ya'ni lori, ẹtọ ni ki a ma'nu ba. Ti awọn oke gbla-gbla ni ki a sọ tabi ti Yinyin, tabi orun ti o nran nigbati o ni ati jẹ oru ọganjọ tabi ti orun ti ki iwọ lasiko ẹrun nilu Hamerfest, tabi ti awọn ti otẹ ilu yi do ti anpe ni (Laplanders) pẹlu aja wọn to ba enia lẹ'ru.

Fun ọjọ kini ati ekeji ti a de ilu Oslo, agbara kaka ni fun diẹ ninu wa lati bere fun omi lati wẹ, bẹ kedere ni oju ọjọ ri ti o si dara. Ninu ile Apejẹ (Hotels) omi tutu ati gbigbona mbẹ l'arọwọto ko si npe ki a to ... omi gbigbona.



Aworan yi nfi awọn Oniwe Irohin lati ilu Nigeria ti nwọn lọ bẹ ilu Norway wo, ni ọnu ọjọ mẹta yi. Eniti o duro ti o nsọrọ yi ni Ọgbẹni Lanre Ladenegan, Ọgbẹni Taju Thompson ni o joko tele, lẹhinna ni Ọgbẹni Odunewu ati Ọgbẹni Effiong, Ọgbẹni Mabinuori ati Ọgbẹni J. Oche, wọn mba Balẹ ilu Vardo (Lord Mayor) sọrọ.

Balẹ ilu na (Mayor) fi Ami Afihan (Badge) ti awọn kọ ọrọ si lara bayi "Freedom of the City" eyiti a le tumọ bayi:- "OMINIRA NILU WA" da awa alejo rẹ l'ọla.

# Igbehin Re Ju

Lati Ọwọ
AKINTUNDE ṢOWUNMI Part III.

Agbelebu te'lomiran wuwo rinrin,
Laigbeleri, o nwọ'nia lọrun;
Ọtọ li agbelebu ti a f'okuta akọ ṣe,
Ọtọ li agbelebu igi botujẹ,
Ọtọ li agbelebu igi ọganwo tabi ti pọnhan,
Ọtọ li ti igi Iroko:
Ọtọ li agbelebu ti a fi igi agun-maniye ṣe,
Ọtọ li ti kor'ko ẹba - ọna.
Emi ko mọ, Edumare nikan re mọ iru yi o fi ṣe agbelebu temi,
Ara mi ọwọn, o wuwo pọ,
Ṣugbọn bi o ti wuwo to, ko wọ mi lọrun, ko ta mi lara,
'Tori ako gbe e kuro niwaju Olugbala;
Gbogbo araiye k'e ma gbọ,
Alanu li Ọlọrun wa;
Ona rẹ re a ko mọ.
Hun! Edumare, ọba ọlọna ara,
Awamaridi ro iṣẹ re dede, ko ye'nia;
Igbi Edumare ba fẹ tan imọlẹ s'ọna enia,
A koko mu okunkun ṣu biri-biri;
Igbi Edumare ba fẹ gb'enia ia,
A mu oliyẹn koja n'iyẹwu iku ọmọ Ọpapa,
Iru iṣẹ ara bayi ti wa nilẹ wa lişẹṣe;
Ligbi a nda'nia toju-timu ka to foliyẹn jọba,
Ka to sọ o d'aisẹ ibikeji Oriṣa.
'Tori ikoko yi ma jadun,
Idi rẹ a gbona jọnjọn, ẹgbẹ rẹ a sun ṣẹnṣẹn;
Ore wa ṣe o ngbọ,
B'aiye enia kan ba berẹ pẹlu ipọnju, k'oliyẹn t'ọpẹ bẹnu,
'Tori igbẹhin ko ni ṣaidun;
Wo apẹrẹ aiye lara Eiyẹle
Eiyẹle ki i b'obi lai b'akọ,
Lẹhin inira mọ pe, idẹra npọtẹṣẹ bọ;
Tun wo apẹrẹ aiye lara itanna ododo,
Wo o la igi ọpẹ, wo o lara wura to dabi erupẹ ilẹ;
Edumare da enia ni isọwọ ọkan mẹta nwọnyi kakiri,
Olukuluku pẹlu ọla, olukuluku pẹlu ogo,
Olukuluku pẹlu iṣoro, kaluku pẹlu itiya,
Isọwọ enia kinni dabi itanna ododo,
Lati owuro Iaiye wọn ti dara,
Ọ'la ati ogo wọn titi di ọjọ kanri, a pọ, pọ, pọ, pọ,
Ṣugbọn igbi ọjọ ba yẹri, ẹwa ododo a fo lọ,
Ogo ododo a yẹra, ọla rẹ a dohun itan,
Isọwọ awọn enia keji dabi igi ọpẹ;
Egun ọgan ati panti a funwọn lọrun l'aṣẹṣẹyọ,
Nwọn o fori yilẹ titi, ki nwọn to goke agba,
Igbi nwọn ba dagba tan ti nwọn a dire,
Titi aiye awọn ko dẹ m'oṣi,
Isọwọ awọn enia kẹta dabi wura,
Wura, lakọkọ ko l'ẹwa, ko l'ogo,
kodun, ko ta, o dabi yanrin;
Igbi wura ba koja l'arin ina, nigba meje tan,
Awa di iwun t'eru-tọmọ njijadu;
Ọrẹ, boya iwọ wa ninu isọwọ wura ninu ẹda
Tani le so, tani le mọ'yen ?
Ohun ti mo wi nijọsi, mo tun wi fun dede ẹni,
E jẹk'a roju duro de igbẹhin;
ko ni buru lati ibẹrẹ titi dopin,
Enia ko ni fi gbogbo ọjọ aiye jẹ'ewuro laitoyin wo.
Ṣebi lẹhin ẹrun a ngi igba ojo,
Lẹhin ọsan a dẹ ar'oru,
Lẹhin inira k'a ma pe idẹra gbọdọ mitingindin :
Toyin yi aiye nku bi eluhọ,
Ẹnyin yi aiye ri ọkọ nyin sarin agbami,
Ẹnyin yi aiye nsi lepete lyn,
E roju, b'omi koro, b'omi tilẹ fẹ pọ jọka lọ,
Igbẹhin re aleyo ata, igbẹhin adun :

A ba wa gbe bukata wa dode
A ba wa gbe bukata wa
Edumare ọba to n'aiye
A ba wa gbe bukata wa.

Ipọri igbo, ki jẹk'ebi p'erin ninu igbo,
Ipori ọdan ọdan ki i jẹk'ebi p'efọn ninu ọdan;
Ipọri Yemọja ki i jẹk'ebi pẹja ninu omi,
Anu Eleda ko ni jẹk'ebi pọmọ enia.

A ba wa gbe bukata wa.
Edumare ọba to n aiye
Edumare ọba to n'aye o
A ba wa gbe bukata wa.

Edumare yi ki jẹki ti nwọnriwọn wọn,
ko n' jẹki ire tiwa wọn,
Olubodi yi ki jẹki t'ẹta ku ta,
ko ni jẹki aiye wa kuta,
Adani magbagbe yi ki jẹ kile alakan gbẹ.
ko ni jẹ k'ọwọ wa gbẹ tojo-tẹrun;

A ba wa gbe bukata wa

Edumare ọba to ni wa.

Edumare ọba to ni wa o

A ba wa gbe bukata wa.

---


## AKIYESI PATAKI

**Bi o ba fe ra Eleti-Ofe tabi o fe polowo oja sinu re,**

LỌ SI:-

**18, Race Course Road,**

OKE—PADI, IBADAN.

**E mu irohin wa tabi ohun to ba je edun okan yin, ki e si ma ka Iwe ELETI—Ofe nigba gbogbo.**


---

No. 96.

## Government Notice No. 1283.

COLLECTIVE PUNISHMENT ORDINANCE (CAP. 34).

Under the provisions of the Collective Punishment Ordinance the Governor - General has directed that an enquiry be held into incidents which occurred in the NSAW Clean Area of the Bamenda Division of the Southern Cameroons during April, 1956, and that a Report shall be made to him thereon.

2. The Governor - General has directed that the enquiry shall be conducted by the following two officers sitting together :-

J. G. C. Allen
G. S. Sowemimo.

3. The said enquiry shall be held at such place and time as the said officers shall direct.

4. It is to be noted that the provisions of the Criminal Procedure Ordinance relating to summoning witnesses, compelling their attendance, and relating to their examination on oath, will apply to this enquiry.

(Sgd.) P. H. G. STALLARD
Acting Secretary to the Governor - General.

---


# ABOKI

JẸ AWOGBA ARUN to lo kiki ka ilẹ Enia dudu.
AJẸBIDAN ni fun IKỌ, LAKUREGBE, IWORA, AKOKORO, SOBIA, AKANDUN, JẸDIJẸDI, ETC.
KOṢE FẸKU ni Gbogbonṣe yi je fun GBOGBO ILE nitorina RA IGO kan loni. Lọdọ:-

**IBUKUN - OLU MEDICINE STORES,**
Amunigun Street, Box 245, Phone 189x, IBADAN,



E 21.
SABONGBRI,
ZARIA,

X 5.
Central Market
Box 2205,
Kumasi,
Gold Coast.

## Irora Ni Orikerike Ati Isan Ara

BOYA ARUN IGBAROKO LOFA



Ise ti KIDINRIN tabi olo - inu nṣe ni lati ko gbogbo idọti ti o mbẹ ni ara danu. Bi awọn Kindinrin nwọnyi ko ba ṣiṣẹ daradara awọn idọti ara na yio ma po si, yio si wa di irora fun enia ni orikerike ninu ara.

Ọna ti a le gba fi ba gbogbo arun yi ja ni wipe ki a ṣe iranlọwọ fun Kidinrin lati ṣiṣẹ rẹ egbogi ti a npe ni DE WITT'S yi lo le ṣiṣẹ na.

Nitori iru arun bayi ni a ṣeṣe egbogi na o si jẹ atura o si nfọ inu enia mọ npa jijẹ ki Kidinrin bere ise.

A ti dan egbogi DE WITT'S yi wo a si ri wipe o dara, Kakiri gbogbo agbaiye ni a nta Ọpọlọpọ iwe ni a ti ri gba lati ọdọ awọn ti arun yi mba ja, ti awọn si ti ri iwosan kiakia.

Kini nda ọ duro ti iwọ ko danwo fun irora tirẹ lọ si ṣọbu egbogi lọ ra ọkan wo.

Egbogi DE WITT'S dara fun Ẹhin didun, Irora Orike, Lakuregbe Igbaroko ati arun Isan ara.

Ohun ti o dawa loju nipe egbogi DE WITT'S yi lẹ eyiti a ṣe tonitoni gbogbo egbogi rẹ l'o si dara.



**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles


## Awon Ọmo Akeko Ni Yaba D'ase Sile

YABA. Irohin ti agbọ ni wipe, awọn ọmọ ti o nkọ ẹkọ iṣẹ ọwọ ni Yaba Trade Centre, binu da'ṣẹ silẹ lori ohun ti a gbọ pe, o ndun wọn lọkan, awọn mejidinlọgọfa lo binu da iṣẹ silẹ.

Ohun ti o mu wọn ṣe bẹ ni wipe Ijọba ko fun wọn ni anfani ẹkọ ọfẹ lọ si ilu Ọba, nwọn ko si ni itelorun pelu onjẹ ti nwọn nfun wọn, awọn ko ni anfani ibiti nwọn o gbe ma mu faaji. Ko si oyinbo tabi Oluko ti o nkọ ni lẹkọ nipa ogbon inu ati ẹgbọn ori. Bi nwon ba si ṣe aṣiṣe, nṣe ni nwọn nge owo wọn.

Iwọnyi ni awọn nkan ti nwọn nfẹ ki ijọba ṣe fun wọn. Nwọn nfẹ ki Ijọba ma fun wọn ni anfani isimi (Leave) ki nwon si ma fun wọn ni ẹkọ ọfẹ. Dipo eyiti nwọn fi nṣiṣẹ wakati meje abọ l'ojumọ, ki nwọn ma ṣiṣẹ fun wakati mẹfa.

Olukọ agba fun awọn ọmọ Ak'ẹkọ na (Principal) ti a npe ni Conki kọwe si awọn ọmọ Akẹkọ to daṣẹ silẹ wipe, bi nwọn ko ba pada si aye wọn ninu ile Ẹkọ na, on yio tilẹkun ile Ẹkọ na patapata.

Ijọngbọn na si mbẹ nilẹ, koiti loju.

## Balogun Okenla Se Bebe

Awọn opitan sọ wipe Balogun Okenla ni ijoye ti o kọkọ gba ẹsin Igbagbọ ni Abeokuta on si ni si ni ijoye ti o kọkọ fi iru oti oyinbo kan ri a npe ni Majamala ṣe alejo. (Rum)


### Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to ṣeṣẹ de, fun oniruru aisan tọkuntin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos




Aworan yi ni ti Emotan, obinrin to gba ilu Ibini la lasiko ogun.


## CARSON'S PAINTS AND VARNISHES




SOLE AGENTS:-
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28 BALOGUN STREET, LAGOS.

ORO OLOTU

## Atago K'eyin Aparo Ohun Oju Wa L'oju Ri

Adura ti gbogbo enia nsba l'ode aiye lojoju o ni ki Olorun maşe jeki a pade agbako Eyi fiban wire Alisonnu buruku ni agbako, ko si si arowolę to raye to agbako, nitoripe iru ni, ki idin l'ebę.

Agbako a ma yo si enia lojiji nigbamiran, nigba pupo, ewe, awon elomiran a ma fi iwa ati işe won p'olowo bi eni np'olowo oja kakiri ilu pe "Eniti o ba ni agbako ki o to fun on"-

Ę s'akiyesi, Ole, omuti, Pa: şaga tabi agbere, abiieni, Olofofo ati Oniwa jandukn, ati awon oniwa buruku miran gbogbo l'o gbe opa wahala dani fun rawon, ti nwon si nwa agbako kiri l'ojojumo- Bi iru awon enia bawonni ba şe alabapade agbako ni'iti agb ko lugo si ti ede ti o şe ena lati pa, eh ti i o w ri oju won i ...

Nit a a ke os ka wa ... ti ... I ti fun en k a p ina aidara ... o de oni ... yo, ti ko si eniti o kun won l'oju, papa emi ti won ra gidi ko ile jo won loju tabi kil'o po? Lode aiye wa oni yi, ti o fere je wipe gbogbo awon omo wa, t'okunrin-t'obirin, ani awon "Dęngę" ni ibiti won ba so'lę si, alaru ni a o ri ko igo oti Bia nibę, eyi ko diwo ki a ma tun ri bi igo Oti gbigbona bi Gin tabi Wisiki bi mejimeta ti awon elegiri na yio pari pelu.

Loju tiwa, oro iru awon enia bayi nigbati nwon ba pade agbako, ko ni ani-ani ninu nitoripe "Atago ko eyin Aparo" ni, eheg ti oju ba wa ni oju nri.

## Agb'owo Ipa da Reluwe Duro

Agbo wipe awon Olotu Reluwe nila kan je gbese bi iwon £76 Adajo si paşe wipe ki awon lo san gbese na Sugbon awon Reluwe ko bikita lati san owo na.

Olori awon Agbowo-ipa t'iijoba yo si Teşan Reluwe, bi oko Reluwe ti gunle beni Agb'owo ipa ba fi oda le oko Reluwe na wipe ko gbodo lo mo.

Nigbati oko yi npę iu, okan ninu awon Loya ti o mbę fun awon Olotu Reluwe na lo san owo na. Nigbayi ni Agb'owo-ipa to tu oko na sile pelu gbogbo awon ero inu oko ki o to şi.

## Ewo lo joju julo

OLOTU
Gba mi laye die ninu iwe irohin re oloyin momo ti ma jade losose fun ogbon ati ibere, lati bere awon nkan nwonyi lodo awon okawe re eyiti nwon ba rope o dara julo ninu awon nkan nwonyi. Reluwe, Oko Oju Omi, Oko Ofurufu, Ero Asoro-magberi, Simeti ti nwon fi nkele, Moto, Eyi ti o ba fesi ki o so idi re ti o fi so pe, o dara julo.

Emi ni
Y A. Agbaje
ara Kumasi.

## Kini Idi Re

OLOTU
Jowo gba mi laye ninu iwe Irohin re olyin momo lati bere lodo awon okawe re itumo ati idi re. Ibere na ni yi.
"Owo wo ni nwon npe ni owo alafia ati kini idi re ti nwon npe e be? Kini nwon ti npe owo keji?

Emi ni
Gongo so
Ara Kişi

## Omo Marun Lekan

KADUNA- A gbo wipe iyawo Olopa-Oba nilu Kaduna bi omo marun lekanşoso sinu ile Iwoşan (General Hospital).

A si gbo pe lehin ti o bi awon omo na, meta ku ninu won şugbon meji mbę l'alafia. Lehin eyi ni awon omo meji na tun ku. Ki Edumare wo iya omo na.





# Lafia Rest House
## MOOR PLANTATION IBADAN.
## CHARGES

Accomodation:
Double chalet consisting of lounge, double bedroom (single beds) bathroom and lavatory,

| | | |
|---|---|---|
| Per person | Sharing | £0 15 0d |
| | Not sharing | - 17 6 |
| Single air - conditioned bed/sitting room, own bathroom and lavatory | | 1. 5. 0 |

MEALS

| | |
|---|---|
| Breakfast | 5. 0 |
| Lunch | 7. 6 |
| Afternoon tea | 1. 6 |
| Dinner | 8. 6 |
| Special lunches (to order) | - 10. 6 |
| Special Dinners ( " " ) | - 12. 6 |

We also cater for non-residents. In addition to normal meals, light refreshments are obtainable.

There is a fully licensed bar on the premises.

DINNER 8/6d.

MENUS FOR WEEK ENDING 19th JULY.

| FRIDAY 13th JULY. | SAT 14th JULY, | SUNDAY 15th JULY |
|---|---|---|
| Coconut Soup | Barley Soup | Puree Crecy |
| Haddock Baked with Tomato | Cod Steak | Horse D'Oeuvre |
| Chicken Casserole | Roast Beef | Roast Lamb |
| Boiled Potatoes | Yorkshire Pudding | Mint Sauce |
| Carrots | Roast Potatoes | Roast Potatoes |
| Beans | Cauliflower | Brussel Sprouts |
| Chocolate Mousse | Beans | Carrots |
| Cheese & Biscuits | Pineapple Ice | Rum Cream |
| Coffee | Cheese & Biscuits | Cheese & Biscuits |
| | Coffee | Coffee |

| MONDAY, 16th JULY | TUESDAY 17th JULY |
|---|---|
| Cream Soup | Baked Bean Soup |
| Fried Fish | Fish Cream |
| Anchovy Sauce | Roast Chicken |
| Mutton Chops | Bread Sauce |
| Mint Sauce | Roast Potatoes |
| Boiled Potatoes | Carrots |
| Carrots & Peas | Peas |
| Sea Foam | Peach Melba |
| Cheese & Biscuits | Cheese & Biscuits |
| Coffee | Coffe |

| WEDNESDAY 18th JULY | THURSDAY 19th JULY |
|---|---|
| Carrot Soup | Vegetable Soup |
| Fish Pie | Fish Scallops |
| Blanquette of Veal | Boiled Ham |
| Butter Potatoes | Chipped Potatoes |
| Carrots | Peas |
| Peas | Chocolate Trifle |
| Strawberry Ice Cream | Cheese & Biscuits |
| Cheese & Biscuits | Coffe |
| Coffee | Coffe |


**E ma ka iwe Irohin Eleti Ofe ki e ma polowo oja yin sinu re nigba gbogbo.**

Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. box 407 Lagos Phone 23579